Ohun Tó O Lè Ṣe Kí Ìdílé Rẹ Lè Jẹ́ Aláyọ̀ (Apá 1)

A gbé e ka orí 14 nínú ìwé *Kí Ni Bíbélì Fi Kọni Gan-an?* ó wà lórí ìkànnì www.jw.org/yo.

OHUN TÍ O FẸ́ ṢE: Ṣàyẹ̀wò ohun tó o gbà gbọ́ àti ìdí tó o fi gbà á gbọ́, wo ohun tí Bíbélì fi kọni, kó o sì mọ bí wàá ṣe ṣàlàyé àwọn ohun tí o gbà gbọ́ fún àwọn ẹlòmíì.



KÍ LÓ LÈ MÚ KÍ ÌGBÉYÀWÓ LÁYỌ̀?

1 ṢÀYẸ̀WÒ OHUN TÓ O GBÀ GBỌ́

Kí lo rò pé àwọn kan máa sọ nípa ìbéèrè yìí?

Kí ni **ìwọ** rò nípa rẹ̀?

Kí nìdí tó o fi gbà bẹẹ̀?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

2 WO OHUN TÍ BÍBÉLÌ FI KỌNI

Ìtọ́sọ́nà Ọlọ́run ló lè mú kí ìgbéyàwó láyọ̀.

(Wo orí 14 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọni,* ìpínrọ̀ 1 sí 4.)

Ka Lúùkù 11:28.

Kí ni Jésù sọ pé ó yẹ ká máa ṣe ká lè máa láyọ̀?

_____

_____

_____

Ka Jẹ́nẹ́sísì 2:18, 21-24.

Báwo la ṣe mọ̀ pé ìgbéyàwó tó láyọ̀ jẹ́ ẹ̀bùn látọ̀dọ̀ Ọlọ́run?

_____

_____

_____



Tó o bá fẹ́ to àga tàbí tábìlì kan tó o ṣẹ̀ṣẹ̀ rà, ó yẹ kó o tẹ̀ lé ìtọ́ni tó wà nínú ìwé tí ẹni tó ṣe é fún ẹ. Bákan náà ni Bíbélì rí, àtọ̀dọ̀ Ẹni tó dá ìdílé sílẹ̀ ló ti wá, ó sì jẹ́ ká mọ ohun tá a lè ṣe kí ìgbéyàwó wa lè máa láyọ̀

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

Àwọn tọkọtaya tí ìgbéyàwó wọn láyọ̀ ń tẹ̀ lé àpẹẹrẹ Jésù.

(Wo orí 14 nínú ìwé *Bíbélì Fi Kọ́ni,* ìpínrọ̀ 5 sí 13.)

Ka Éfésù 5:23, 25, 28, 29.

Bó tiẹ̀ jẹ́ pé Jésù ò fẹ́yàwó rí, báwo ló ṣe jẹ́ àpẹẹrẹ rere fáwọn ọkọ?

Ka 1 Kọ́ríńtì 11:3 àti Éfésù 5:33b.

Kí làwọn ìyàwó lè rí kọ́ lára Jésù bó ṣe fi ara rẹ̀ sábẹ́ Ọlọ́run? (Tún wo 1 Pétérù 3:1-4.)

Kí ló mú kó o gbà pé ìlànà Ọlọ́run ló dáa jù kí tọkọtaya máa tẹ̀ lé?

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania

3 ṢÀLÀYÉ ÀWỌN OHUN TÍ O GBÀ GBỌ́

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Ìwé ayé àtijọ́ ni Bíbélì, ọ̀rọ̀ inú ẹ̀ ò lè wúlò fún ìdílé mọ́ lóde òní.

O LÈ SỌ PÉ…

Ó ṣeé ṣe kí ọ̀pọ̀ èèyàn gbà bẹ́ẹ̀. Àmọ́ ohun tí mo gbà gbọ́ yàtọ̀ síyẹn torí pé…

_____

_____

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Tó o bá fi èrò ẹni náà sọ́kàn, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹsẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

TÍ ẸNÌ KAN BÁ SỌ PÉ…

Ohun tí Bíbélì sọ nípa ipò orí ń mú káwọn èèyàn máa fojú kéré àwọn obìnrin.

O LÈ SỌ PÉ…

Àwọn kan ti túmọ̀ ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lóòótọ́. Àmọ́ bẹ́ẹ̀ kọ́ ló rí nínú Bíbélì, ìtẹ́ni tí Bíbélì fún tọkọtaya buyì kún àwọn obìnrin. Bí àpẹẹrẹ…

_____

_____

Ẹsẹ Ìwé Mímọ́ wo lo máa kà fún ẹni náà?

_____

Tó o bá fi èrò ẹni náà sọ́kàn, báwo lo ṣe máa ṣàlàyé ẹsẹ Ìwé Mímọ́ náà fún un?

_____

www.jw.org © 2016 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania